# IGBAGBỌ́ TI O MU ÈRÈ WÁ

## Marku 5:21-43

### ẸKỌ 80 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ṣugbọn li aisi igbagbọ́ ko ṣe iṣe lati wù u; nitori ẹniti o ba ntọ̀ Ọlọrun wá kò le ṣai gbagbọ́ pe o mbẹ, ati pe on ni olusẹsan fun awọn ti o fi ara balẹ wá a" (Heberu 11:6).**

**I Ipadabọ Jesu**

1. Awọn eniyan n fẹ lati pade Rẹ̀, Marku 5:21; Luku 8:40; Johannu 12:32; Jeremiah 29:13
2. Jairu rẹ ara rẹ̀ silẹ niwaju Kristi, Marku 5:22; Luku 8:41; Matteu 9:18; Orin Dafidi 33:8
3. Igbẹkẹle nla ninu Jesu fara hàn, Marku 5:23; Matteu 8:2, 8-10
4. Jesu dahun ẹ̀bẹ atọkanwá, Marku 5:24; Matteu 9:19; 8:5-7

**II Aṣeti Ẹda -- Aṣeyọri Ẹlẹda**

5. Obinrin naa ti jiya pupọ, Marku 5:25; Matteu 9:20; Luku 8:43
6. Ọpọlọpọ onișegun ti ṣe aṣeti lati wo o sàn, Marku 5:26
7. Ọkàn ti o gbagbọ́ ri itusilẹ, Marku 5:27-29; Matteu 9:21, 22 Luku 8:44
8. Jesu mọ pe obinrin naa wá sọdọ Oun pẹlu igbagbọ́, Marku 5:30-32; Matteu 9:22; Luku 8:45, 46
9. Igbagbọ rẹ̀ mú ere wá fun un, Marku 5:33, 34; Luku 8:47, 48; Heberu 11

**III Iyè Nipa Igbagbọ́**

10. O bá irẹwẹsi nla pade, Marku 5:35; Luku 8:49
11. Jesu mu obinrin ti n banujẹ naa lọkan le, Marku 5:36; Luku 8:50; Marku 9:23
12. Lai fi ẹgan awọn eniyan pè, Jesu tun ṣe iṣẹ iyanu nla miiran, Marku 5:37-43; Matteu 9:23-35; Luku 8:51-55

## ALAYE

**Titẹwọ Gba Jesu ni Apa Keji (Iwọ-Oorun) Okun**

Ẹ wo iyatọ ti o wà laaarin bi wọn ti tẹwọ gba Jesu ni "apa keji okun" ati idagbere ti wọn fi sin In jade ni Gadara! Ó ti wo ẹ̀rù jẹ̀jẹ̀ ara Gadara sàn, ọkunrin ti o ti maa n daya fo awọn eniyan naa fun igba pipẹ, sibẹ awọn eniyan naa kọ Jesu, wọn ni ki O lọ kuro lọdọ wọn.

Ṣugbọn nigba ti Jesu yọ si "apa keji okun" ogunlọgọ eniyan ni wọ́n pade Rẹ̀. Gẹgẹ bi iṣe Rẹ̀ nigba gbogbo, O maa n fi ara hàn fun gbogbo awọn ti o ba wa A tọkantọkan. Ọkàn Rẹ̀ maa n lọ si ọdọ awọn ti o wà ninu irora, paapaa ju lọ awọn ti n wo O fun iranlọwọ. Olukuluku ẹni ti o ba tọ Ọ wá pẹlu igbagbọ́ ti ri iwosan nipa ọwọ́ Agbára Rẹ̀. Awọn ti wọn tọ̀ Ọ́ wá nipa jijẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn ti ri oore-ọfẹ idariji ẹṣẹ wọn gba eyi ti o jẹ́ pe Oun nikan ṣoṣo ni O le fi fun ni.

Ọkan ninu awọn ti o tete kọ pade Rẹ̀ ni Jairu ti i ṣe olori sinagọgu, ẹni ti o bẹbẹ pe ki Jesu wá mu ọmọbinrin rẹ̀ lara dá. Jairu mọ aṣẹ ti Ọmọ Ọlọrun ni lori ohun gbogbo, o si fi tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀ mu ẹbẹ rẹ̀ wá. Ipo rẹ̀ gẹgẹ bi olori sinagọgu sọ ọ di eniyan pataki laaarin ilu, ṣugbọn o mu ọkàn irẹlẹ ko si ka ara rẹ̀ si nnkan kan nitori o gbà pe Kristi ni Ẹni giga ju lọ lori ohun gbogbo ti o wà ninu ayé. O wolẹ lẹsẹ Jesu lati sọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ̀, o fi ẹmi isin hàn nipa ṣiṣe bẹẹ. Jesu kò dá Jairu lẹbi nitori sisin ti o sin In yii, ṣugbọn O tẹwọ gba a nitori o tọna ki o mọ̀ pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe, ani Kristi ti O n bọ wá. Awọn alaigbagbọ tabi awọn ti o sẹ́ agbara Kristi, ki i ri ibukun gbà lati ọdọ Ọlọrun!

**Jairu ati Igbagbọ́ Rẹ̀ ninu Kristi**

Jairu wá pẹlu ọkàn igbagbọ́ ati nitori igbagbọ́ rẹ̀ a mú ọmọbinrin rẹ̀ lara dá. O ṣe dandan fun un, ki o fi igbagbọ́ rẹ̀ hàn nigba ti iroyin de pe ọmọbinrin rẹ kú, o tun ṣe dandan bakan naa ki o "duro jẹ" pẹlu ọkàn igbagbọ́ naa. Iṣẹ kin-in-ni ti igbagbọ́ hàn gbangba ninu iṣesi ti ode ara, eyi ni ẹbẹ tọwọtọwọ fun aanu ati agbara iwosan lati ọwọ Ẹni Ami Ororo nì. Iṣẹ keji jẹ ti atọkanwa patapata, nitori ki o to sọ gbolohun ọrọ kan, idaniloju ti de pe "Má bẹ̀ru, sá gbagbọ́ nikan." Wo bi igbagbọ́ ààye ti rú jade lọkan rẹ̀ bi o ti gbọ́ ọrọ naa ti o jade taṣẹtaṣẹ ! Bi okunkun tilẹ ṣú dùdù, ti o dabi ẹni pe loju ẹda ireti kò si, ani bi ẹmi tilẹ bọ́, sibẹ aṣẹ sa ti jade, o si duro bakan naa pe "Má bẹ̀ru, sá gbagbọ́ nikan."

Igbagbọ ní ère ti rẹ̀. Ọmọbinrin (naa) parada ni igbọran si ọrọ Oluwa Ẹni ti o ni agbára lori iku ati iyè. Iyè pada bọ̀ sinu oku ara ti o ti tutu nini naa, o si rìn. Ara ọmọbinrin naa dá ṣáṣá, o tun di ọmọ ti o n mu ayọ̀ ba gbogbo ile pẹlu ẹwa ti ọ̀dọ́ ati ireti rere fun ọjọ iwaju ni igbesi-ayé rẹ̀. Eyi jẹ èrè nla fun igbagbọ bi ti ọmọ kekere ninu Ẹni naa ti ko si eredi kan ti o fi ṣe iyemeji ifẹ Rẹ̀, aanu Rẹ̀, ati agbara Rẹ̀ ti ki i ba a ti!

**Obinrin ti o fi Ọwọ́ kan Iṣẹti Aṣọ Kristi**

Ṣugbọn, ki i ṣe eniyan kọọkan ti o wà nibẹ ni ọjọ naa ni o ni anfaani lati wolẹ lẹsẹ Jesu pẹlu ẹbẹ fun iranlọwọ Rẹ̀ tabi lati ba A sọrọ lojukoju gẹgẹ bi Jairu ti ni anfaani lati ṣe. Iwe Mimọ́ sọ fun ni pe ọpọlọpọ eniyan n wọ́ tẹle Jesu bi O ti fi eti okun silẹ lati lọ si ile Jairu, obinrin kan si wà laaarin ero ti oun naa n fẹ iranlọwọ ti o ṣe pe Jesu nikan ṣoṣo ni O le fi fun ni. Obinrin yii ko rẹwẹsi nitori oun kò ni iru anfaani ti olori sinagọgu ni.

Obinrin naa, pẹlu, ni igbagbọ́. Bi a ba si wà ni àyè lati ṣe idajọ lori bi igbagbọ́ olukuluku ti pọ̀ tabi lagbara tó, a fẹrẹ le sọ pe obinrin yii ni igbagbọ́ ti o tayọ ti gbogbo awọn eniyan ti o wà nibẹ lọjọ naa. Nitori ailera rẹ̀, idaamu

ọpọ eniyan ti o yi i ká, ati idiwọ iṣẹ miiran ti Ọmọ Ọlọrun ni lati boju to, gbogbo iwọnyi mu ki o di dandan fun obinrin naa lati lo iwọnba anfaani ti o ṣi silẹ fun un. Eyi naa ni ó si mú lò.

O ti jiya fun ọpọlọpọ ọdun lọwọ awọn oniṣegun. Wọn ti gba gbogbo owó rẹ; nisisiyii o ti wá di akuṣẹ, alaini nnkan kan ati olokunrun patapata. Boya o tilẹ ti lọ lati ilu kan de ilu miiran ati lati ọdọ eniyan kan de omiran, ibikibi ti o ṣe e ṣe fun un lati dé, ki o le ri iwosan, ṣugbọn ohun ti o ri mu bọ̀ ni iranti gbogbo aṣeti awọn oniṣegun, ati jijẹ oró nipa iṣẹ wọn – ati àrùn kan naa ti o gbe lọ! O dabi ẹni pe awọn ohun ti o ti ṣẹlẹ sẹyin yoo bi igbagbọ rẹ wó ninu ohunkohun ati ninu ẹnikẹni. O ṣe e ṣe, o si tilẹ rọrun, ki obinrin yii ti sọ ireti nù patapata ki o si ti gba kámú. Ṣugbọn oun, bi ti Jairu, fi igbagbọ́ rọ mọ Ọlọrun nigba ti o ba iṣura iyebiye ni pade, iṣura ti n fun ni ni iyè.

O jẹ onirẹlẹ ọkan kò si ka ara rẹ yẹ lati yọ Olukọni lẹnu. Otoṣi obinrin kan lasan ni i ṣe, lai ni ohun iṣogo kan tabi iyi kan laaarin ẹgbẹ. Kò ni nnkan kan lati mu wa siwaju Oluwa bi ko ṣe àrùn ati ẹ̀ṣẹ rẹ̀. Ṣugbọn ni ọjọ yii o di mimọ̀ fun un dajudaju pe Jesu ko ni nnkan kan i fi iyi aye tabi ogo rẹ ṣe, kàkà bẹẹ, O mura tan lati ṣe iranlọwọ fun gbogbo ẹni ti o ba wá siwaju Rẹ̀, nitori O ṣe iranlọwọ fun obinrin yii. Iṣe rẹ fi ẹmi isin tootọ ati igbagbọ hàn, nitori o mọ pe bi oun ba sá ti le fi ọwọ kan iṣẹti aṣọ Rẹ̀, agbara ti o ba jade lati ara Ọlọrun-di-eniyan tó lati wo oun sàn. Kò ro pe o ṣe dandan ki oun ṣẹṣẹ maa yọ Oluwa lẹnu ki si i ṣe dandan pe ki O gbe ọwọ le oun lori. “Bi mo ba sá le fi ọwọ́ mi kàn aṣọ rẹ̀, ara mi yio da” ni ipinnu ti o ki i laya lati ki ori bọ arin ero lọ sinu agbo lọhun nibi ti Oluwa ti n rin lọ.

“Ninu agbo ti o sunmọ Ọlọrun pẹkipẹki” ni a ti n ri ibukun Ọlọrun gbà. Ki i ṣe lẹyin agbo ti inù bẹẹ ni eniyan ti le mọ adun ati ibukun ifarahàn Rẹ̀. Ko si ẹni ti o fi ọwọ kan fa ayé mọra, ti o le ṣe alabapin agbara ti o jade lati ọdọ Ẹni ti O fi ọrọ ẹnu Rẹ̀ dá ayé. Bi eniyan kan ba fẹ ri ibukun Ọlọrun gbà, ẹni naa ni lati làkàkà gidigidi lati wà ni irẹpọ timọtimọ pẹlu Jesu, ki o si ni ọkàn igbagbọ́ ati idaniloju.

Fifi ọwọ kàn pẹlu igbagbọ́ ni ti rẹ̀ jẹ́, nitori o wi pe, “Bi mo ba sá le fi ọwọ́ mi kàn aṣọ rẹ̀, ara mi yio da” (Marku 5:28). Ki i ṣe ifi-ọwọ-kàn ti o òwòran lasan. Oun kò dabi awọn ti n kọlu U bi O ti n kọja lọ. Fifi ọwọ kan jẹ̀jẹ̀ ni ti rẹ̀. A fẹrẹ le fi oju ri i bi o ti n la aarin ero lọ ninu irora aisan, bi awọn iyoku ti n jijakadi lati ri Oniṣẹ-iyanu nla naa. Ti rẹ̀ rekọja eyi bi o ti rọra n gbesẹ sun mọ Ọn lọ. Boya ọwọ rẹ ni O kọkọ na jade; lẹyin naa o fi ika kan tabi meji kan aṣọ Rẹ̀; lẹyin naa boya o si tun di iṣẹti aṣọ Rẹ̀ mu pẹlu ọ̀wọ̀ ati imi-ẹ̀dùn ọkàn fun iranlọwọ - lẹyin naa o fa ọwọ́ rẹ̀ mọra o si fi aṣọ naa silẹ.

Ara rẹ bọ̀ sipo! Ẹmi titun wọ agọ ara rẹ! Gbogbo wahala atẹyinwa fẹ lọ gáu. Okun ati ilera tun pada sinu agọ ara rẹ̀ lẹẹkan si i. Kò tun ni lati fi ọwọ kan aṣọ Jesu mọ́, ju eyi ti o ti ṣe, fun aṣepé iṣẹ naa. Iṣẹ naa ti ṣe. O rin ṣáṣá boya daradara ju bi o ti rin fun ọpọ ọdun sẹyin.

Ṣugbọn iṣoro miiran de si i, nitori Oluwa yara beere pe, “Tali o fi ọwọ́ kàn mi li aṣọ?” Dajudaju ibeere naa le. O ṣe awọn ọmọ-ẹyin ni kayefi, nitori ọgọọrọ eniyan ni wọn n bá Jesu lọ loju ọna tooro naa, kò si ṣe e ṣe ki eniyan má fi ara kan An. Ṣugbọn Jesu kọju si obinrin naa, o si mọ lẹsẹkẹsẹ pe Ẹni ti oju Rẹ̀ ri ohun gbogbo, ti O si mọ ohun gbogbo ti mọ ohun ti oun ṣe. O fi ibẹru ati iwariri wolẹ lẹsẹ Rẹ̀ nitori o mọ nisisiyii siwaju si i pe ni tootọ Jesu ki i ṣe eniyan kan ṣá. O kuku sọ ohun gbogbo fun Un!

Idahun Jesu jẹ itunu ati itura fun obinrin naa gẹgẹ bi yoo ti jẹ itọni fun awa paapaa. Ṣugbọn ohun ti obinrin naa ri gbà nibẹ ju iwosan ti ara lasan lọ. “Mã lọ li alafia” ko le ni itumọ miiran ju pe Ẹni ti I ṣe orisun alaafia tikara Rẹ̀ ti dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i ati pe o le maa lọ ki o si gbe igbesi-ayé titun pẹlu ara dida ṣaṣa ati ọtun iwa nipa ọrọ Kristi ara Galili. Igbagbọ rẹ̀ ninu Kristi naa ati agbara Rẹ̀ ni o fun un ni gbogbo iranwọ yii.

**Igbagbọ jẹ́ Ohun Danindanin**

Ninu Heberu 11:1 a ka pe, “igbagbọ́ ni idaniloju ohun ti a nreti, ijẹri ohun ti a kò ri.” O rekọja nnkan ti a n mọ̀ lara, o ju ohun ti a le ri tabi ti a le fọkàn rò lọ. Ohun ti o daju patapata ni, ti o si lagbara lati mu gbogbo otitọ ti ọkàn n fẹ gẹgẹ bi ẹda ṣẹ. Igbagbọ si tun jẹ ohun ti o so wa pọ̀ mọ́ awọn otitọ iye ainipẹkun! Igbagbọ jẹ kò ṣe e má ni, nitori Ọrọ Ọlọrun sọ fun ni pe lai si igbagbọ́ ko ṣe i ṣe lati wu Ọlọrun (Heberu 11:6). Eniyan ti o n bọ̀ niwaju Ọlọrun gbọdọ gbagbọ, gẹgẹ bi Jairu ati obinrin alaisan ni, pe Ọlọrun n bẹ, ati pe O jẹ olusan-ẹsan fun awọn ti wọn ba fi tọkantọkan wá A. Igbagbọ́ ni i mu ni wu Ọlọrun!

Igbagbọ̀ a wọ inu ọkàn nipa gbigba Ọrọ Ọlọrun gbọ́ ati gbigbọran si aṣẹ Rẹ̀. Ori kọkanla Heberu fun wa ni akọsilẹ awọn akọni ninu Ọlọrun ti wọn ti jagun molu, ti wọn ṣe nnkan ribiribi fun Ọlọrun nitori wọn ni igbagbọ́. O jẹ agbara ati itilẹyin fun wọn ni akoko aini wọn ti o ga ju lọ, ni akoko idanwo kikoro, ni akoko ọfọ tabi ni akoko igbogun tì. O jẹ iràwọ̀ atọ́nà ti o mu wọn de ilẹ ileri nipa ti ẹmi, on lo si jẹ ki o ṣe e ṣe fun wọn lati ri ilu Ologo ti Ọrun ti wọn si wò kọja ohun gbogbo ti i ṣe ti ayé yii. Igbagbọ ni ohun ti o ṣọ̀wọ́n ju lọ patapata ninu aye, bẹẹ si ni, ọfẹ ni fun olukuluku ẹni ti o ba fẹ ni in. Awọn ti o ba si ni in le ba Ọlọrun rin, wọn yoo gbadun ibukun Rẹ̀, wọn yoo si maa foju sọna fun ifarahàn Rẹ̀ gẹgẹ bi awọn akọni Ọlọrun wọnni ti wọn ti lọ gba ere wọn.

**A WỌN IBEERE**

1. Nigba ti Jesu pada bọ̀ lati ibi ti o gbé ti wo ẹlẹmi eṣu ni sàn tán, iha wo ni awọn eniyan ibẹ kọ si i?
2. Iru ipo wo ni Jairu wà laaarin awọn eniyan ti o n gbe?
3. Ki ni iṣesi rẹ̀ niwaju Jesu? Njẹ o tọ́ bẹẹ?
4. Ki ni idahun Jesu nigba ti O gbọ́ ẹbẹ Jairu?
5. Ta ni gbiyanju lati fi ọwọ tọ́ Jesu bi O ti n lọ?
6. Njẹ obinrin naa ri ohun ti o n fẹ gbà? Ọna wo ni eyi gba ri bẹẹ?
7. Ki ni imọran ti Jesu fun olori sinagọgu nigba ti o gbọ́ iroyin ikú ọmọ rẹ̀?
8. Ki ni ero ọkàn awọn eniyan naa ni ile Jairu si Jesu, ki si ni idi rẹ̀ ti wọn fi ni iru ero bẹẹ?
9. Bawo ni a ṣe dá igbagbọ́ baba ọmọ naa lare?
10. O ha yẹ ki a bẹru lonii lati gbẹkẹle Oluwa? Oun kò ha le ṣe ohun kan naa fun wa bi?